**Ogun Ita'ja**

E Polowo oja yin sinu Iwe Irohin Eleti-Ofe, Kia L'oja o ta.

ELETI OFE
A-NJU-WON KO SE WI-EJO

**Akiyesi Pataki**

A fi iwe yi se ikede si awon Asoju iwe irohin Eleti-Ofe kakiri agbaiye wipe, enikeni ti ko ba fi owo ti o ti je ranse si wa, no pe k-jo, ako si ni fi iwe irohin ranse si enibe mo.

VOL. X No. 603. LAGOS, SATURDAY, DECEMBER 20 - Dec. 26, 1958 KOBO MEJI (2d).

# Ijoba Ile Mende Sedekun Fun Edegbeta Omo Ile Nigeria, Alafia Ti De.

ABIDJAN. Edegbeta awon omo ile Nigeria ti awon Mende ti gbero le lori lati wa pada lo silu won nitori rogbodiyan kan ti o be sile larin awon ara Togoland ati awon Dahomi pelu Ijoba ile Mende (Ivory Coast Authority) eyiti a gbo wipe awon omo ile Nigeria ko mowo-mese ninu oro na, sugbon nitori alafia won ni nwon se sa asala lo si ibudo Ijoba ile Mende, ni a gbo pe oro na ko ni je be mo.

Olotu Ijoba ile Nigeria fi ye wa wipe, awon Alase Ijoba ile Mende ti kowe si won pe awon enia na ti pada si aye won nile Abidjan a ko si ni wa won pada lo sibikan mo. Awon ara agbegbe Osun ati Oyo lo poju ninu awon enia na.

A gbo wipe awon ara ile Nigeria nwonyi ti kuro nibiti nwon sapamo si olukuluku won si ti lo si ibugbe won nile Mende.

LAGOS RACE CLUB
**CHRISTMAS MEETING**

Friday 26th Saturday 27th December, 1958, Thursday 1st ... Saturday 3rd and 10th January, 1959.
Racing Starts at 2.45 p.m. each day of the Meeting

DECLARATION

To be made at the Secretary's Office between the hours of 5 p.m. 6 p.m. on the day preceding the day of the race. Except on the First and Second days (26th and 27th December, 1958) when it will be made between the hours of 9 a.m. and 10 a.m.

ADMISSION TICKETS (ADVANCE PURCHASE)

ADMISSION TICKETS for the Meeting can be purchased in advance at the Secretary's Office in the Paddock between the hours of 5 p.m. and 6 p.m. on the day preceding the day of the race. Except on the First and Second days (26th and 27th December, 1958) when these can be purchased between the hours of 9 a.m. and 10 a.m.

ADMISSION 7/6d per day
including Entertainment Tax

CHILDREN

No children under the age of 14 years will be permitted to enter the Members Enclosure.

## Oga Agba Central Bank Nigeria



Ogbeni Roy P. Fenton ni en'ti Alabojuto owo (Finance Minister) yan lati je oga agba patapata ni Central Bank ti nwon nko si Ita Tinubu.

Oloye Okotie Eboh lo yan a sigo na nitoripe Ogbeni na je omo Gesi ti a gbo pe o ti nsise ninu Bank ilu Gesi ri, ko si si Banki kan nilu Oyinbo ti o siwaju Banki ti England. Ogbeni Fenton yi je Onimoran fun won ni Banki na.

Nwon ti se ofin wipe gbogbo owo titun ti ao ma na lati inu Central Bank ni yio ti ma lade, Oloye Okotie Eboh so wipe Central Bank ti Eko je omo kekere legbe awon asiwaju re, eniti o si ti mowo iru ise ti o ye ki a m nse ni Central Bank na ni Ogbeni Roy P. Fenton.

# LAGOS RACE CLUB

## CHRISTMAS MEETING

### Friday 26th Saturday 27th December 1958, Thursday 1st, Saturday, 3rd and 10th January 1959.

| FIRST DAY | START |
|---|---|
| RACE No. 1 Six Furlongs Handicap Bottom Division | 2. 45 p.m. |
| RACE No. 2 Six Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 15 p.m. |
| RACE No. 3 Six Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 45 p.m. |
| RACE No. 4 Eight Furlongs Handicap Middle Division | 4. 15 p.m. |
| RACE No. 5 Eight Furlongs Handicap Middle Division | 4. 45 p.m. |
| RACE No. 6 Eight Furlongs Handicap Middle Division | 5.15 p.m. |
| RACE No. 7 Seven Furlongs Handicap Top Division | 5.45 p.m. |
| RACE No. 8 Seven Furlongs Handicap Top Division | 6. 15 p.m. |
| **SECOND DAY** | |
| RACE No. 1 Nine Furlongs Handicap Bottom Division | 2.45 p.m. |
| RACE No. 2 Nine Furlongs Handicap Bottom Division | 3.15 p.m. |
| RACE No. 3 Six Furlongs Handicap Middle Division | 3.45 p.m. |
| RACE No. 4 Six Furlongs Handicap Middle Division | 4.15 p.m. |
| RACE No. 5 Six Furlongs Handicap Middle Division | 4.45 p.m. |
| RACE No. 6 Six Furlongs Handicap Middle Division | 5.15 p.m. |
| RACE No. 7 Five Furlongs Handicap Top Division | 5.45 p.m. |
| RACE No. 8 Five Furlongs Handicap Top Division | 6.15 p.m. |
| **THIRD DAY** | |
| RACE No. 1 Eight Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 00 p.m. |
| RACE No. 2 Eight Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 30 p.m. |
| RACE No. 3 Nine Furlongs Handicap Middle Division | 4. 00 p.m. |
| RACE No. 4 Nine Furlongs Handicap Middle Division | 4. 30 p.m. |
| RACE No. 5 Nine Furlongs Handicap Middle Division | 5. 00 p.m. |
| RACE No. 6 Six Furlongs Handicap Top Division | 5.30 p.m. |
| RACE No. 7 Six Furlongs Handicap Top Division | 6. 00 p.m. |

| FOUTH DAY | START |
|---|---|
| RACE No. 1 Seven Furlongs Handicap Bottom Division | 2.45 p.m. |
| RACE No. 2 Seven Furlongs Handicap Bottom Division | 3.15 p.m. |
| RACE No. 3 Five Furlongs Handicap Middle Division | 3,45 p.m. |
| RACE No. 4 Five Furlongs Handicap Middle Division | 4.15 p.m. |
| RACE No. 5 Five Furlongs Handicap Middle Division | 4.45 p.m. |
| RACE No. 6 Five Furlongs Handicap Middle Division | 5.15 p.m. |
| RACE No. 7 Eight Furlongs Handicap Top Division | 5.45 p.m. |
| RACE No. 8 Eight Furlongs Handicap Top Division | 6.15 p.m. |
| **FIFTH DAY** | |
| RACE No. 1 Five Furlongs Handicap Bottom Division | 2.45 p.m. |
| RACE No. 2 Five Furlongs Handicap Bottom Division | 3.15 p.m. |
| RACE No. 3 Five Furlongs Handicap Bottom Division | 3.45 p.m. |
| RACE No. 4 Seven Furlongs Handicap Middle Division | 4.15 p.m. |
| RACE No. 5 Seven Furlongs Handicap Middle Division | 4.45 p.m. |
| RACE No. 6 Seven Furlongs Handicap Middle Division | 5.15 p.m. |
| RACE No. 7 Seven furlongs Handicap Middle Division | 5.45 p.m. |
| RACE No. 8 THE GOVERNOR-GENERAL'S CHALLENGE CUP Ten Furlongs | 6.15 p.m. |


## IJO AGUDA KO GBO-DO JERAN

ROME. Pope John [illegible] [illegible] ti Aguda [illegible] December 1958 ti bo si ojo Friday, on [illegible] Aguda ko gbodo [illegible] kan eran jije lojo na. Ki nwon se ojo na ni ojo irono kakiri agbaye.

## OWE YORUBA

Gunugun sore lo fi pa lori, Akalagbo sore lo fi yo gege lọrun, bẹ ẹ ore ko npani laa-laa nikan lo nko wa ba ni.


## Independence Celebrations

### SUGGESTIONS

If you have any original ideas regarding the form that the Federal Celebrations should take in Lagos, please put your ideas in writing, and post them to the :-

**Independence Celebrations Officer,**

34 - 36 IKOYI ROAD,

LAGOS.

All suggestions will be considered.

## Itan Ajapa Ati Ekun

Apa Ix

Lati owo EṢỌ

Ka mase tun fa ọrọ yi gun lọ titi mọ, bẹni Ẹkun wa ilu na ni awati. Lọjọ ti aisun oku baba ọba ku ọla, Ẹkun bẹrẹ si ta ṣaṣa kakiri, o nya ojuile awọn ọmọ ẹranko kakiri, o mbere bi awọn ba ri ilu on, a ko ri ẹniti o le sọ ohun kan nipa ilu na.

Ko ni pẹ titi ki o ma ṣe ku ọla, ọjọ aisun oku baba ọba pe, ese gbogbo awọn ijoye, ọlọla, gbajumọ ati awọn serekode ilu lo peju-pesẹ sibi aisun na.

Nigbati o ṣe ni awọn iran eku wẹrẹ wẹrẹ bẹrẹ si ede. Ẹkun ti lọ sona lẹnu ọna abawọ Afin ọba. Oluku-luku eku ti o ba de ti o ba fi oju kan Ẹkun mbiti o gbe doro si ti o si koro oju, ti oju na pọn bi ẹjẹ, yio kọkọ ke wipe Kabiyesi o! eni ko ṣa soro o? Ẹkun yio da wọn lohun pe, o ṣoro, ṣa lu ilu rẹ kia ngbọ! nitori ẹnikan ti gbe ilu temi lọ. Bi eku na ba si fọwọ le ilu rẹ, yio dun bete bete, bete. Nigbana ni Ẹkun yio fun laye pe ki o kọja, bayi ni Ẹkun nṣe fun gbogbo awọn ti o selu wa sibi aisun.

Iroyin ti kan lọ ba Ajapa nile wipe bayi-bayi ni Ẹkun nṣe fun gbogbo awọn ti o ba selu wa sibi aisun. Ajapa jẹ ijoye kan ti o niyi ’niwaju ọba ipo rẹ si ju ti Ẹkun lọ lọdọ ọba; ọba na papa ko si jẹ fi rọ Ajapa sere.

(Wọ yoku lọsẹ ewe Karun)

FOR THE BEST IN HIGH QUALITY BREAD
Dinner Rolls, Wedding Cakes, Tea Cakes and Confectionery.
COME TO
**ODLS BAKERY**
BAKERS AND CONFECTIONERS
Director
Hon. Solanke Onasanya
M.H.A. F. Inst. B.B. Dip Bakery
72 OKE-IYEGBA ROAD,
Sura Lere.

*Itan ẹni t’o ṣ’owo t’o b’ode padi*

# Ọgbẹni Peter Ezeli

## pẹlu The United Africa Company jumọ sise po fun idẹra:



KO pẹ ti Ọgbẹni Peter Ezeli jade ni ile iwe ti o bẹrẹ ise keke tita rẹ, ni ilu Warri ati Onitsha. Ki o to bẹrẹ si ta keke ti ara rẹ, baba rẹ l’o mba sọ ’gba. Lẹhin na, o bẹrẹ si ta awọn ẹya ara keke, titi o fi di ẹni ti nta odidi keke l’ọwọ. Ṣugbọn igba t’o mọ pe ’nu ofo ni akoko ti U.A.C. bẹrẹ si pin ni diẹ diẹ ninu awọn Raleigh bicycle lati ma ta.



Ninu ọdun 1953 ni Ọgbẹni Ezeli ti di ẹni ti nra oja tire lọwọ gedegbe l’ọwọ U.A.C. Nigbati o tun di ọdun t’o tẹle e, o di ẹni ti awọn nta awin oja fun. Imọran rere ati onituru iranlọwọ, ti Ọgbẹni Ezeli ti gba l’ọwọ awọn alamọran awọn U.A.C, l’o so o di ọlọrọ, ti iye ti npa l’ọdun si fi di gobọi. O ti gba ẹni kan ti nsan owo osu fun lati ma ba a ta oja rẹ; awọn mẹta l’o si tun gba, ti awọn ko ni ise miran ju lati ma ba a to awọn keke ti nta ni ile itaja titun rẹ, t’o ṣi si ilu Warri. Gbogbo irin ise ti awọn nlo ni ’be awọn egbẹ U.A.C. l’o pese rẹ.

Ọrọ akiyesi, ti Ọgbẹni Ezeli afi si ’waju ara rẹ t’osan t’oru ni: Ṣiṣe daradara; ma ya si ’bi ya s’ohun: owo ti o ba nse, jẹ k’o ye ọ d’ekanna. Ọla ti Ọgbẹni Ezeli ni fi han gbangba pe ọgbọn pẹ ninu ọrọ akiyesi rẹ yi.



Ọgbẹni Ezeli ... U.A.C ... U.A.C. ... U.A.C. ... United Africa Company ... [illegible]

THE UNITED AFRICA COMPANY OF NIGERIA LIMITED

# ELETI - OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

Kosoko Street, Lagos "ELETI - OFE LAGOS"

P. O. Box 367 Phone 23370

VOL. NO. X 603 LAGOS, SATURDAY DEC 20 - DEC 26 1958


## Keresimesi Odun De

Lekansi, a tun ngborun ọdun atiya ọjọ ibi Jesu Kristi. ki a to ri ọsẹ kan si ti Iwe Irohin wa Eleti-Ọfẹ, Oloyinmomọ yi yio tun jade, ọdun Keresimesi yio ti de, yio si ti şi'kọ rẹ lọ, gẹgẹbi awọn ọdun miran ẹlẹgbẹ rẹ ti awọn ti fi igbakan bẹ wa wo nihin ati nibi gbogbo agbaiye.

Tani ninu ọpọlọpọ ẹnyin ọkawe wa ti ko mọ nipa ẹkọ ati ọrọ iyebiye ti a ri ka ninu Iwe Mimọ Bibeli ti o jẹ wipe ẹnu Olukọni nla na l'o ti jade ani Kristi Jesu? Kosi, fun iwọn o'idi ọdun mẹta gbako ti o fi nṣiṣẹ ti a ran lati ode ọrun fun awọn enia ti o wa ni asiko tirẹ.

Gbolohun kanṣoṣo pere ni a o yọ fi gba ẹnyin ọkawe wa ni'yanju ninu ọrọ ti o ti ẹnu Olukọni ati Olulana nla na jade, ti o jẹ ẹkọ fun tọ'mọde-t'agba awa ọmọ enia l'ode aiye. Nigbati awọn adakamẹkẹ enia bi lere ọrọ gannu - ngande, ani ọrọ agbanimọbo, wipe "O tọ lati ma sanwo ode fun Kesari tabi ko tọ?

Nje bi enia ba bi ẹlomiran lere ọrọ mọnafiki bayi aiyọ," Kini o tilẹ se ti a fi nsanwo omi fun Ijọba wa, nje irẹjẹ na kọ niyẹn? njẹ ẹlomiran ko ni fi ninu lakoye rẹ f'ẹnukọ bi? boya nipa fifi esi ti o le mu ki Ijọba na ro'jọ wipe o ta kọnrọngbọn si Ijọba? Bẹkọ ni ti Jesu, ẹniti a o se iranti ayajọ ọjọ - ibi rẹ ni ọjọ mẹfa oni ri.

O sọ fun wọn pe ẹ fi owo ode kan han mi, nigbati nwọn si fi han, o bi wọn lere pe aworan ati akọle tani eyi? Nwọn si dahun pe ti Kesari ni. Jesu wa fi pakute ọrọ na mu wọn, o wipe "Ẹ fi ohun to nṣe ti Kesari fun Kesari, ẹfi ohun to nṣe ti Ọlọrun fun Ọlọrun" Irufẹ irọ ẹkọ bawonyi pọ jọjọ ti o ti ẹnu Olukoni na jade. Nitorina, a ki ẹnyin okawe wa nibi gbogbo.

Ẹ ku ewu odun :!!


## Imroan Fun Enyin Abiyamo

Enyin Abiyamọ e wa ra ỌMỌRẸLA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama jẹ ki ọmọde ri orun sun daradara o dara fun ẹjẹ, ikọ ati orisirisi arun miran ti o ma mba ọmọ ja ni asiko ehin. Ọpọlọpọ abiyamọ lo ti lo egbogi yi fun ọmọ wọn ti won si sọ wipe o dara pupọ fun awọn ọmọde

ỌMỌRẸLA BABY MIXTURE

(Şile Meji Abo 2/6d Fun Igo Kan)

O w Lọdọ

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemists)

10, VICTORIA STREET, LAGOS.


## OLOYE BEYIOKU NILU OYINBO



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Oloye O. A. F. Beyioku Ẹniti o jẹ akọwe ẹgbẹ osise Marine ni ebute Apapa lasiko ti o mbe nilu Oyinbo ẹ lọ se aṣoju fun awọn osise ọgba Marine. Ogbeni Archibald ni oruko oyinbo ti o duro 'nba soro nṣe




# Oniwe Irohin Enia Dudu Nilu Oyinbo



Enitl a nwo ninu aworan ti o nfi ero gbohun gbohun (Telephone) soro ni Ogbeni Alade Odunewu ti o nse Olotu Daily Service nilu Eko ni o nse iwebie fun iwe irohin kan nilu Oyinbo ti awon npe ni Herald Ogbeni Odunewu lo osu mefa ni ilu Oyinbo lati fi ko nse Iwe Irohin.

## ODUN KIRIYO TUN DE!

Nigba lailai, ti owo ko po nile aiye gegebi ti isisiyi bi odun Keresi-mesi ba mbo bayi ni iwo yio ma gbo ti awon ooilu gangan yio ma lulu bayi wipe "Esu s'omo'kunrin Lo nfi goin sere" lati ma fi ki awon gbajumo ninu esin Kiriyo.

Iwo yio si tun ma gbo iru orin bayi lenu awon sasa were Kiriyo nigbati nwon ba je ti nwon mu tan wipe:-

Iku la ba bo, a, bi forisa sile. Ojo awure, lo gbe weli-weli de o, Iyan la ba je, a ba f'amola sile, Ojo awure lo gbe weli-weli de o.

Lotun-losi ni iwo yio ma gburo ilu gangan. Gbogbo awon obinrin Kiriyo yio ma para lo kakiri oja, nwon ti so aguntan, ewure ati nkan hawe-ni mole fun ase odun Keresi-mesi.

Sugbon l'ode toni, odun Keresi-mesi ko tun ni ariwo mo, nwon ko fe ki enia ba won je, ayafi ki nwon ba enia je. Ranti, lodun 1909, ojo keji ti nwon se odun Keresimesi ni nwon pa eran odun ileya igbadun po lodun na. Awon Kiriyo isisiyi bi nwon ba ti pe alejo wa sodo won, ni iwo yio ma gbo pe "Why se late" "o ti se pe igbin bayi" nigbati alejo na ba gbo bayi, ko ha ni pada sehin bi?

## Itan Ti O Ti Inu Odu Ifa Jade

Awon enia pataki-pataki nigba lai-lai, ti awon je eni-ti oruko won han titi di oni yi.

Tani Ogun Onire? Ilu kan ni a npe ni Ire, ibe si ni a gbo wipe Orisa Ogun wole si. Eniti o koko joye Onire je omo Ogun, lakaaiye osin mole Olorun, on lo lo gbe ogun ti Babalawo re lehin ti o ti ba se adehun pe, on ko ni gbogun wa silu re mo, nitori idi eyi, ni Babalawo na so o di okuta titi di oni yi.

Tani Alaragba? Okunrin kan olowo, oloro ti Babalawo re so fun wipe, ki o rubo, ki o se etutu, ki awon omo re ma ba woku tan lekan-soso. O ko, ko tubo ko setutu, o seti gbonran si ebo o se aran igbo si Esnielu. Nigbati o se ile wo pa gbogbo awon omo re nigbakanna

Agbefawo-bi ewu-Babalawo kan ti o kegan awon omo Awo re, nigbati o nlo si ajo, nwon ni ki o ru ki o ma ba jeti'oro tiko modi, o ko o seti gbonran si ebo o se aranigbo si Esu o si lo si ajo na a si be lori nitori oro ti ko mo idi re. Onitode Okan ninu awon omoba Olofin ni ile Ife Oyelagbo eniti gbogbo ara ilu korira re ti nwon si le jade kuro ni arin ilu nitori iwa ibile re sugbon asehinwa asehinbo o tun pade wa joba Durogbure-Omo oba Ewi nile Ado Ekiti ti awon ara-kunrin re korirare nitori ife ti baba won ni si nwon ki i mole nwon si fa a ni ern si ode Ondo Sugbon nigbehin, o di olowo, o di oloro tobe ti gbogbo awon ara re tun pada wa teriba fun.

## ODOMODE DI OGBOLOGBO ELEWON

IKEJA Omokunrin kan ti Oruko re nje Lawrence Michael ti o to omo Ogbon Odun ni ojo ori re, ni o ti here si w'ewon lati nkan bi odun medogun s'ehin.

Omokunrin yi tun lo fo sobe kan ni Adeyemi Street, ni Mushin ninu osu May 1958, o si jikeke Basikulu meji ti o je ti Ogbeni Samuel Andrew.

Nigbati ejo okunrin na de iwaju adajo o duro lailmira niti ti awon fi ka esun ole mo lorun, adajo fi s'awon odun meji o sunjada o si wipe modupe sa. Eyi lo di igba ogoji ti ogboju ole yi ti nlo s'ewon.

# Oniwe Irohin Ile Nigeria



Enia a nwo ninu aworan yi je okan ninu awon oni-we irohin ile Nigeria ti o lo fun ilo iwaju ninu ise iwe irohin nilu Oyinbo. Nibiti otutu gbe mu oniwe irohin o a tobe ti o fi di oja mo orun, Oyinbo ti o nse atona re ko tile mo pe otutu mu rara.

## Ibinu Ko Da Nkan Suru Ni Baba Iwa

Iroyin kan wa wipe omobinrin wundia rodo-rodo kan, lo wo oko ero (Bus) Ijoba Eko, ti o nlo si ona idi ero. Nigbati omo wundia na de ibiti ero uduro ni Mosalasi ti o fe bo sile ibe ni oloko ero na ti buso wipe, ko ni bo sile ayafi bi o ba sanwo oko.

Wundia na so wipe, on ti san owo fun oloko na nigbakan, on san owo ti Eko fun, on si tun sanwo ti Yaba fun eto wo ni oloko na ni ki o to tun wa bere owo miran lowo on; ni omobinrin na ba fi tulasi bo sile. Sugbon oloko na binu wipe ko ni lo.

Nigbati ko jeki omobinrin na lo ibe ni ija ti de nibiti awon mejeji gbe weya ija, ni irohin ti lo ba iya wundia na nile ni o ti nsare bo lo ri oloko ti o nlu omo re tarata ti o nsare bo abara lo ko ti oloko (Conductor) ni ija ba tun bere ni perewu, olopa lo wa laja na.

Nigbati ejo de kotu, adajo so pe nitori ti awon ba alafia ilu je ki enikokan lo san Poun marun marun tabi ewon osu kan.

Ibinu ko da nkan suru ni baba iwa. E ma se suru fun ara nyin.

## Awon Owe Ile Yoruba

1 Gbedo-gbedo ko le gbe agogo, alo lo leke ko le lo Baba, alagbede ko le ri ojugun, iro lo nporo fun iro alagbede kan kole ro ike. Sigidi ti ko li enu ni on yio soro, iro lo nporo fun iro.

2 Iro ni Babalawo npa ko ri ifa, iro ni Onisegun npa ko ri oogun, awon abo Egungun ko ri egungun ko ri egungun, awon abo orisa ko ri orisa Olorugbe ko jewo, atunmije bi olorun, eke tan ni si ija ekun tan o wa fi oron alse si apo eni

3 Awon Ikoko ni awon le gbedo. Opelo ni awon le lo leke, Awarebe ni awon le wan a o ... tani je I odo Akoko ... an tani je ... leke ... lo un ... Awarebe bora.

4 Ki Eko ... gbo ko ... fun ... ki Aregbegba gbo ko ... fun omo Ere ni ... ki Alahamebo gbo ko ... fun awon ... were-were ni ... won.

5 Bi ... bi Erin, yio ... bi ... bi Efon yio ... bi ... bi Ila, Ila yio ... bi ... bi Ikan yio ... ese, bi ... bi ... ko ni gbo.

6 Adaba ko je epa, ko ... epa. Kanna kanna ko je eree Gomfori ... ipa epa ohun ti a ba ... ...

7 Bi a ba gbo ... enia, a ka je ... sugbon bi a ba gbo ... Olorun ... ni a nyinbon ... Ka ... lo.

8 Oku ... ti o ... ogod ... je ... loju Erin ... Ekun ... lan ni a ati ... bi ... de ... ise aja ... bi iko ... a gbe ... omo lo.

9 ... o kinni lehin fi egan si owo ... a ni ki o fe ni loju fi ... eon, ... a ni ki a fi ehin ti ki a mu oyan didan ganyin-ganyin lo nfon si mo.

## Awon Agbe Lo Be Ara Won Wo



Awon ti a nwo ninu aworan yi ni awon agbe ile Nigeria ti nwon lo be awon agbe ile Ghana wo. Ninu aworan yi ni a nwo awon agbe ile Ghana ti nwon na pade awon agbe ile Nigeria, awon si duro papo ya aworan yi.

Lapa otun awon ti nwon duro ni awon agbe ile Nigeria ati awon ti o duro ni apa osi ni awon agbe ile Ghana.

## Arun Soponna Ti Wolu, E wa Ko Nomba

Osisegun ilera ti o ntoju ilu so wipe, ijoba lesin, arun soponna ti wo ilu Eko. Ki olukaluko enia wa ko nomba ... ara re ati ile re pelu ati wipe arun na ti nran kakiri ile yi bayi.

Ose mela ni ijoba yio fi ko nomba fun gbogbo enia, e ko o fun ara nyin, iyawo ati omo nyin pelu.

Ibi ... ti ao yan ... si Isin Eko lati ... ko nomba fun gbogbo enia Ki e ma ko awon enia nyin lo ... ko ni duro si ... awon ... yio ma ... lo ... awon ... lati lo nipa fun won nibe Ni odun to koja. Oke merinla enia ni nwon ko nomba ... ... ati ... osi mefa ... awon enia ti ... fun ... oke meji enia.

Emoye fi ara nyin sere

## HOGAN BASSEY BORI NILE AMERIKA



Bassey ... ija nile Oyinbo, ... ohun ti o sele si lote yi ko sele si ri. A gbo pe ija emewa ni nwon fe ... ba ara won ja.

Nigbati ere won na ... ekeja ara Mexico fi ese ... le Bassey ni agbonrin o si subu yakata. Sugbon nibiti nwon gbe nka eka fun ti o di merin, kiakia ni Bassey dide dide o si ... ija re lo.

Awon omobinrin na so wipe nigbati Bassey subu bayi ... awon ara ile Mesiko ... tobege, nigbati nwon ho ... ni Holywood ariwo won ... Washington.

Nigbehin ija na, Bassey bori ... hangna ti Hogan ... di ...

### OMO ONI IBADAN NLO SILU OYINBO

Ogbeni Ademola Oni ti o nse omo bibi inu (Contractor) Oloye T.A. Oni eniti opo enia mo ti nwon si npe ni Oni Oke-Ibadan ni a gbo wipe o nlo silu oyinbo bibi eko ti o ... laipe yi fun ... ... eko.

## Itumo Ala

Gbogbo ala ti enia nla Fo ni itum o si yẹ ki ẹnikẹni ma ṣe akiyesi ala rẹ
Banki - Bi enia ba l a l a wipe, on nfi owo si Banki tabi o ngba owo nibẹ, tabi o tilẹ wọ ibẹ o jade ki ẹni na ṣọra rẹ nitori awọn ole ki aw.n ma ba gbe ni owo lọ.
Ọgẹdẹ- bi enia ba lala ri eyikeyi ninu ọgẹdẹ, tabi o jẹ ẹ oluwa rẹ yio ṣe konge ire laipẹ.
Ẹrujẹjẹ-bi o ba lala ri ohun kan ti ẹru si ba ọ ti o fi taji, ki o ṣọra ki ọwọ ọta maṣe tẹ ọ.
Jamba-bi o ba lala pe Jamba kan fẹ ṣe ọ lojuran ṣugbọn ki jamba na to ṣẹlẹ o ti taji ewu lọ lori rẹ
Ejo-Bi o ba lala ri ejo nla ti ẹru ba ọ, ti o si sa ki o ṣọra nibi iṣẹ, bi ẹru ko ba ba ọ iwọ ko sisa titi o fi ji ọta ibi iṣẹ rẹ ko ni le ṣe ọ ni ibi bi o ba pa ejo na, buburu ti nwọn ro si ọ yio da le w.n lori, ṣugbọn bi eyi na ba kere awọn ọmọde lo nṣe inunibini siọ bi o ba jẹ ejo nla bi Ere, Olori ibiṣẹ na tabi Ijọba lo ndiṭẹ si ọ
Diti- bi o ba lala wipe eti rẹ di iwọ ko si gbọrọ mọ ewu nlacla kan yio kọja lọ lori rẹ
Bujẹ-bi o ba lala wipe ohun kan bi ẹranko tabi bu ọ jẹ edekoyede yio ṣẹlẹ larin iwọ pẹlu obinrin kan, ija yio si le ṣẹlẹ
Kana-Kana- bi o ba lala ri ẹiyẹ kana kana nfo lọ loju Sanmọ ọfọ kan yio ṣẹlẹ si ẹni na, ṣubọn bi o ba ma tabi a dee mọlẹ, tabi o mbẹ ninu Keji ohun rere yio de si oluwa rẹ.
Kọkọrọ- bi a ba tilẹkun mọ ọ, ti iwọ ko ri ọna gbajade amodi nla kan yio ṣe ẹni na bi o ba jẹ kọkọrọ kọmbọdu ohun kan yio ṣonu lọwọ rẹ bi o ba jẹ pe, o wa wa kọkọrọ na o si ri, iwọ yio ṣe wahala ki o to ri okan na.

---


## Kere o !

Ati ni orisirisi o g u n German to ṣẹṣẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ ki o to tan.

J. A. AJAO BROTHERS

MEDICINE STORES

7, Egerton Road Lagos





# Nigerian Ports Authority

## INVITATION TO TENDER

Tenders are invited by the Nigerian Ports Authority for the purchase of such scrap materials as the Authority may offer for disposal (with the exception of any items which may be separately offered for sale) during the period 1st January, 1959 to 30th June, 1959, in Apapa Dockyard, Apapa Quays, Customs Quay, or any other particular point where the Authority may have scrap metal for disposal in the Lagos or Apapa Areas.

2. Tenders indicating a price per ton should be submitted in sealed envelopes marked "CONFIDENTIAL - TENDER FOR SCRAP" and addressed to the under - signed so as to reach him not later than Saturday, 3rd January, 1959. Late tenders will not be considered.

3. The successful tenderer will be required to remove, at his own expense, whatever scrap is available for sale (with the exception mentioned above) during the six month period indicated, within 7 days of the Authority's notification of such availability and will be required to make the necessary arrangements at his expense for all the scrap removed to be weighed in the presence of a representative of the Authority.

4. The Authority do not bind themselves to accept the highest or any tender.

**Bayo Kehinde**

Ag. Secretary to the Authority.

N. P. A. Notice No. 247.
17th December, 1958

---

## IPADE IJỌ ỌRUNMILA NILE IFẸ

O le ni igba Ikọ lati orisirisi ilu ni ayika Orilẹ-ede ni ẹba Odo-Ọya (Nigeria) ati lati ọwọlẹ ilẹ Faranse ti wọn peju si ipade „AJỌ, yi, eyiti aṣe lọjọ kejọ Ọjọ Aje, osu O p e p e Odunni-(8/12/58), ni Gbọngan-Alajẹṣe (Community Centre), lati fi ipinna si eto „ATUNKO- ILE- ADAIYEBA ILE IJUBA ODUMARE, ni ogangan (biti ni ọgangan ti Ile lo[illegible] ti wa tele.

O le ni ẹgbẹjila ọkẹ (£600) ti a ri ko jọ. A pinnu a si ṣa adehun kikọ ile Ijuba na pẹlu Onişẹ Ikọle (Building Contractor) na s' ẹgbẹrin ọkẹ (£4000). Ki o ba le bẹrẹ iṣẹ na ni kiakia A fun ni owo ibẹrẹ gẹgẹbi adehun ti a se.

Lẹhin ipade, gbogbo Ikọ de Afin lọ k'i Alaiyeluwa o b a Adesoji Aderemi, II, Ọlọfin Oni Ile O fi ebun owo ti o jọju ta Ikọ lore ati, pẹlu igba [illegible] ti o jọju.

## Orin Afolabi Si Abudu Eleja

Orisa ni yio gba Abudulai loko Olowo

Iinale ko nsingba

1 Bi osu Ojun kan ti fe le Abudulai fe sanwo ile, Ile lo ji ni owur kutu ha', Ooi, fun emi Abudulai loni, Sati Masai pese fun mi Ni ọsankọnà loni Mase jeki oju ti i mi rara Ki onile le 'jeki asimi. 2. Abudulai ju egigi s'odo O sorikodo o nreti esi O sa ni' kan gbadura kika Onke ayu kan ninu tira. Ọlọrun to da emi si, Ko ni salai pata sii Lakọkọ o wọ egigi re Pako Nigba keji o gbe eja Abo Ọba lo pese Abo yio pese kuta 3 Oniba a rẹ nlọ, o mbọ, Sa wo Ọlọrun Ọlọna ara. O yọuda Kutu Olodo kan eyiti o ta ni ọkẹ marun o fi ọkẹ meji sowo ile. O ra gele meji abo fomọ rẹ. O da abọ sile Ọlọrun, O fi iyoku gbọ ti ata.

(Koiti pari)

abiorin kan ti o nje Dorcas Adebọla ni on pelu orogun re nse nse gbolohun aso si ara won nitori oro kan ti o selo larin awon mejeji.

Nigbati Dorcas se iresi ti o fe je tan, ogbo wipe o fi ibinu da iresi na si orogun re lara eniti oruko re nje Abigael Ọmọlọmọ ninu osu October.

Oro na di nkan ti awon ọlọpa lọwọ ninu te nwon si gbe oro na dewaju Adajọ.

Adajọ ni ki Dorcas lọ san Poun mejilelogbọn si kotu lebin na ki o lọ san Poun mewa fun Abigael owo egbo ti o da si lara, bi ko ba 'ti san ki o lọ gbewa osu merin.

### ARA ORUN KAN LỌ ROJỌ NI KOTU

Egungun kan ti nwon npe ni Alemolẹbin ni a gbo wipe o ma nna gbogbo awon ti ko ba fun ni owo a ti ma fi iya je wọn.

O wa na ọmọkunrin kan ti o wa se Iṣe Birikila nilu na, ibẹ ni oro na ti dogun awon Ọlọpa. Egungun na rojo wipe ọkunrin na ko bọwọ fun on nigbati o ri pe on mbọ bẹni o si gbegbo awọn egbe re yoku ti nwọn nsare si fila wọn fun on sugbọn kaka ki o kuro ni arin wọn o joko nibe o si nfojudi on.

Awọn adajọ kotu ibilẹ sọ wipe gegebi aṣa ibilẹ, gbogbo awọn ọmọ Yoruba lo ni lati bọwọ fun aṣa ibilẹ, sugbọn Egungun na jebi fun nina ti o na ọmọkunrin na, nitorina ki o lọ san sile marun tabi ewọn ọjọ meji.

### PỌUN MEJILELOGỌN FUN IRẸSI GBIGBONA

ILESHA. A gbọ irohin wipe

# Nigerian Ports Authority

## INVITATION TO TENDER

Tenders are invited by the Nigerian Ports Authority for the purchase of the under-mentioned scrap materials :—

| Lot. No | Location | Description |
|---|---|---|
| 1 | Calabar | 1 Machine Saw |
| 2 | ,, | 2 Refrigerators, as one lot |
| 3 | P/Harcourt | 12 12-Volt Batteries, as one lot |
| 4 | ,, | 7 6-Volt Batteries, as one lot |
| 5 | Apapa Dkyd | 1 Electrolux Refrigerator |
| 6 | ,, | 7 Water Heaters, as one lot |
| 7 | ,, | 4 Ceiling Fans & Regulators as one lot |
| 8 | ,, | 3 Table Fans as one lot |
| 9 | ,, | 1 Dinghy D 76 (Steel) |
| 10 | ,, | 497 4-gallon Empty Kerosene Tins as one lot. |

2. The above items may be inspected on application to the following officers of the Authority between the hours of 8 a.m. and 12. 30 p. m. not later than 29th December, 1958 :—

| | |
|---|---|
| Lots 1 & 2 | Harbour Master, Calabar |
| Lots 3 & 4 | Senior Stores Officer, Port Harcourt |
| Lots 5 to 10 | Senior Stores Officer, Apapa Dockyard |

3. Tenders should be enclosed in sealed envelopes marked "CONFIDENTIAL - TENDER FOR SCRAP" and should be addressed to the Acting Secretary, Nigerian Ports Authority, Private Mail Bag 2588, Lagos, so as to reach him not later than Thursday, 8th January, 1959.

4. The successful tenderer in each case will be required to remove the material at his own expense within 21 days of acceptance of his offer.

5. The Authority do not bind themselves to accept the highest or any tender.

**Bayo Kehinde**

Ag. Secretary to the Authority.

N. P. A. Notice No. 248.
17th December, 1958.





### ORIKI BAMWO

Bamwo de, alajela ọmọde agbomala bi orisa, akọkọluko ogun ti ndamọ l'ekun igbona, atata ogun ti npo tutu re warawara a je bi idan, a gba bi ota ibọn. O s'abiku di ikugbagbe, o s'ọmọ ti nhebin l'ore, Ikọ ri i sa, Iba ko l'ọna tagiri, aiperi ri n'ekun iyọnu Ologbọla f'ọmọ ti nyagbe orin o kapa inu wọ, o ju ṣọdi l'alupa gbogbo abiyamọ ayọ sese. Ela ri i o roju, Ọrere ri i o na'gbe ho'ra Esi npa lemọ lodaleso. ore ikoko, kosemani awọn abiyamọ, eni araiye njijadu ra. O de ile Ibo, o doga o de ile Hausa, o d'oba gbogbo Oorisegun l'o yi pe ko leghe, gbogbo ọmọde lo nfẹ ọ fun ilera

100 KEKERE 2/6d - 100 NLA 4s owo ọkọ 1/6d fun Igo kan

THE EGBA TRADING ARADAN STORES

18, Denton Bridge Street, P. O. Box 2 Ebute - Meta





Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company 28, Kosoko Street Lagos P. O. Box 467 Phone 25799